**Owe**

KITA-KITA OMO TI ARISIKI, KI A SISE BI ERU KO DA NKA

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

Asoje

XIII No 802 LAGOS SATURDAY OCTOBER 28, – NOVEMBER 3, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)

# KOTU NLA PASE WIPE IJOBA GBOGBO-GBO KO NI ASE IWADI NATIONAL BANK.

EKO - Kotu nla ti ijọba Apapọṣe ti ilẹ Nigeria paṣẹ nilu Eko ni owurọ ọjọ Jimọ (Friday) ọjọ kẹta-din-lọgbọn oṣu October 1961, wipe Olotu Ijọba Apapọṣe (Prime Minister) ko ni agbara lati ṣe iwadi National Bank.



SIR ADETOKUNBOH ADEMOLA
Adajọ Agba Ilẹ Nigeria

Awọn Ofin kẹta ati ẹkerin ti Alaṣe ofin Ijọba mu wa ko mọyan lori, nitorina, ki nwọn da ọjọ na pada si Kotu Giga niwaju Adajọ Ọgbẹni Onyeama.

Ki Ijọba Apapọṣe lọ san adọjọ pọnun at adọjọ ṣile (150 Guineas) owo irin ẹsẹ fun Oloye Bayọ Doherty.



OLOYE BAYO DOHERTY
(Emi'An'peri)



ALHAJI ...
Olotu Ijọba Apapọṣe

## Ejo Abetele De Kotu

ABA - Obirin Abileko kan ti o jẹ Hausa, Ashabi Audu, ti nwọn fi sun ẹsun pe o fẹ fun adajọ ni obi nilu Aba ni adajọ na fa le ọlọpa lọwọ.

Nigbati Adajọ Ọgbẹni J.O Kassim njẹri ni o so fun Kotu wipe on gbo iro wipe ọdaran na nwa on bọ lati fun on ni nkan, ni on fi fi ero isoro ba awon olopa soro lati fi olopa meji ranse si on. On si fi won pamo si ibiti o dara ninu ile on.

Laipe ni odaran na de pelu apilewo lowo re ti o mu igo oti Wisiki kan ati eyin adie wa fun on. Nigbati on bere lowo re wipe kini o wa fi se? odaran na bere si be on pe esu l'o ti on se be e.

Lesekese, ni on fa le olopa lowo.

## Oloye Onitana W'aja

EKO - Gbukẹ ni a gbọ iku Oloye Tadeyọ Onitana ti ilu Eko, ni owurọ ọjọ Alamisi (Thursday) ọjọ kẹrindin-lọgbọn oṣu October, 1961, nwọn si sin oku rẹ ni ọjọ Jimọ (Friday) ọjọ kẹta-din-lọgbọn oṣu yi kanna. Oloye Onitana jẹ ọkan ninu awọn Ijoye Idẹjọ nilu Eko,

**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited**
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA.
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE ABA KANO ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
15 THROGMORTON AVENUE, E.C.2
Manager : F. O. ...
Telephone: London Wall 4703
Cables & Telegrams: Natbanigr London
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi ...
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Ojojumo Ni Awon Oyinbo Gesi Nse Awari



EWO awọn kinni robo-robo ti o wa ni aiclewo ti a nwo niru aworan yi, je ogun kan ti nwon tun sese se awari re fun iwosan arun awa eda enia l'aiye.

## Alagbara Kan Pe Awon Alagbara Meji Nija

ENUGU - Ọkunrin kan ti nwọn npe ni Bende ni o pe awọn alagbara meji nija wipe ki ẹgbẹ oṣere ipinlẹ Ila-orun ṣe eto lati pe'de ki awọn danrawo,

Nitu iwe rẹ ti o kofi pe won nija na lati Elu-Elu, Bende so wipe on ti ni agbara ju ti awon alagbara meji, Ọgbẹni Kilwe Nwachuku ati Caterpiller Amadi ti ilu Ahoada lọ.

O tun sọ wipe on le ru mọto ela ẹlẹsẹ mẹfa sori on, ki on si fa ọgọrun enia ni afa ma yipo. O lẹ akọwe ẹgbẹ oṣere Ila-orun ni Enugu, ki o kọwe si awọn alagbara meji na ki awọn wa danrawo.

## ELETI - OFE DARABA

## Nigerian Ports Authority.

INVITATION TO TENDER

CONTRACT FOR SUPPLY OF LABOUR FOR

(a) NO. 9 BERTH, APAPA QUAYS

(b) NO. 9 TRANSIT SHED APAPA QUAYS.

The Nigerian Ports Authority invite tenders from Contractors to supply experienced labour with adequate suspervision for the handling of cargo at the NO. 9 Berth, Apapa Quays.

2 Tenders Which must be submitted on forms provided by the Authority and returned in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL TENDER FOR LABOUR," should be addressed to the Secretary to the Authority, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, so as to reach him not later than 4 o'clock in the afternoon of 15th November, 1961.

3. The issue of an official form of tender will be subject to a deposit of £10, payable to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The deposite will be returned on receipt of a bona fide tender.

4. Application from only labour contractors who have had experience in similar work will be considered, and the Authority do not bind themselves to accept the lowest or any tender.

**Bayo Kehinde.**
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice NO. 639.
23rd October, 1961.


## E Ma Se Fi Omi Sofo




**E kilo fun awon omo nyin ki nwon mase lo omi ni ilokuilo**

# Olotu Ijoba Pada De

Eko - Olotu Ijọba Apapọṣe, Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa, pada de si ilu Eko ni owuro ọjọ Monday ọsẹ yi, lẹhin ti o si o ju-ọna Reluwe ti o lọ lati Kuru si Bauchi.



Awọn Oniwe irohin bere lọwọ re wipe kinifẹro tirẹ si ọrọ ti Olotu Ijọba ilẹ Ariwa, ọlọla Alhaji Sir Ahmadu Bello, sọ nipati Ajọ Igbimọ Majẹobajẹ Agbaiye ati iwa agabagebe awọn ijọba alagbara lori etu olero ti awọn ndanwo.

Ọlọla Abubakar dahun wipe "Ẹnikẹni ni ẹtọ si ero ọkan rẹ" on ko si le sọ nkankan si. Awọn Ọlọla enia ti o lo pade rẹ ni idi ọkọ ni Ọgbẹni T. O. S. Benson, Ọgbẹni R. A. Njoku ati Dokita O Ikejiani, Alaga Igbimọ Apapọṣe ise Reluwe

---

## Ijoba Kongo Ko Adehun Tshombe

LEOPOLDVILLE - Ijoba Kongo ti ko adehun Tshombe ti ilu Katanga ti o fe ya kuro lara Kongo lati ma a ṣe ijoba tirẹ lọtọ.

Ọgbẹni Joseph Ileo, ti iṣe alaṣẹ irohin Ijọba so wipe ijọba yio wa ona ti o fi pari yiya kuro ilu Katanga laipẹ.

# Itan Ibukun Ju Owo Lo

(Lati ọwọ Ọlajide Babson)

Ni Igba laelae Ọrẹ meji kan wa, oruko ekini ama jẹ Ibukun Jowolọ, orukọ ekeji ama jẹ Ọlọla, iyen je ọmọ ọba, ọrẹ won yi jinlẹ pupọ ti won si ti wa fun bi ogun ọdun won a ma ba ara won je, wọn a si ma ba ara won mu. Ọre kori-kosun ni won.

Nigbati o ya, won fi ọmo ọba yi jẹ oba ni ilu na, sibe-sibe, won tun mba ọre won lọ, Ibukun Jowolọ yi je otoṣi. Talika paraku ti o je wipe ko ni ẹwu meji, ekisa aṣo lo ma nlo mọra, pelu e na omo ọba ore rẹ yi ko ye ba rin. Bi enyin ra ti mo pe bi enia ba ti di Ọba tabi Oloye, o ṣoro lati ma ri ni igba gbogbo. Ṣugbon ọmo ọba yi ma nṣun Ibukun Jowolo ọrẹ re ni asiko ti nwon le ri ara won.

Lẹhin ti ọre rẹ yi ba ti di ọba o so fun Ibukun pe ki o wa wo on Ibikun si ṣe be, o lọ wo nigbati won ṣọrọ tan ti asiko si lo to fun ọba ore rẹ yi fun Ibukun ni apo owo kan (£100). Ṣugbọn o kọ lati gba apo owo na o si tun sọ wipe Ibukun ṣa ni on nfẹ, o si pada si ile rẹ. Ọba yi bọ si agbaja, o wo titi pe kini ore on lero lati sọ pe on ko fe owo, Ibukun ṣa ni on nfe.

Ni igba ẹkeji o ni ki o tun wa ki on, won tun

(Wo yoku loju ewe ketin)


# OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA BAWO, NI YIO TI ṢE LE RA MIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

## E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe

Losose

## Ewon Osu Meta Fun Ole Toji Ehoro

KABBA - Jimọ Bello ti awọn npe orukọ ọmọkunrin kan ti ọmọ ọdun meji din-logbọ ti Kotu ẹdaran ilu Kabba ṣa konko ẹwọn oṣu meta mọ lara fun ole jija.

Jimọ Bello lọ ji Ehoro kan yan lẹnu okun ti Thomas Osenewo dẹ ni Oko Ogagu, ni ọjọ keji-dinlogbọn oṣu September, ọdun yi

Lẹhinti nwọn rojọ tan ni Adajọ ṣe idajọ ẹwọn oṣu meta le lori.

Bakanna ni Adajọ ju Ajayi Ayegbabu sẹwọn oṣu meta fun iṣu merun ti o ji ko ni oko Oguya ti iṣe ti Innocent Mkwunna, ni Kabba kanna.

## OPOLOPO ENIA F'ARAPA

ONITSHA - Ọpọlọpọ awọn enia ni o f'arapa nigbati agan ija bẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ N.C.N.C. ati ọmọ ẹgbẹ Dynamic ti Dokita Obi n'ilu Onitsha ni ọjọ ọsẹ (Sunday), a tilẹ gbọ pe mọto kan ti o jẹ ti ẹgbẹ Dynamic ni nwọn baje nigbati nwọn nja ija na.

A gbọ wipe ohun ti o fa ija na ni oran ti awọn ọmọ ẹgbẹ mejeji nkọ fi bu Olori ẹgbẹ wọn nigbati nwọn nṣe ikede fun ibo.

Ọlọpa ko ma ṣa kẹni ṣugbọn Ọlọpa ti ṣe ikilọ fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ ati Olori wọn, wipe ki kowa lọ so agbe ọ mọ'di, ki awọn maṣe huwa jagidi-jagan mọ

## ITAN IBUKUN JU OWO LO

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

ṣe bi won nti ba ara wọn ṣe tẹle, ni igbati o tun nlo ọba mu lo si agbala nibiti awon iyawo rẹ wa ti ẹnikeni ko ni aṣe lati de, afi ọba ni kan. Ọba wo titi, o fun ni iyawo to lewa ti o ṣese fe Ibukun ko lati gba, o ni Ibukun ṣa ni on nfe. Ọro yi su ọba orere yi to be ti ko le jeun, ti o nro ohun ti ọre re yi ni on nfe.

Nigbati O di ẹketa, o ni ki o wa ki on, nigbati Ibukun de wọn tun nṣe bi nṣon ti nṣe, ọba wo iyewu lo, o lọ ṣi isale apoti re lati fun Ibukun ni ewu etu, eyiti o je pe bi ode ti o larinrin ba ya lati lailo, lo nilati lọ, ọba koiti fi ọrun kan rara, Ibukun kọ ko tun gba ewu etu na.

Ọba wa bi lere pe kini Ibukun ti o fe lati ọdọ on ? O si dahun wipe, bi ọro atata kan, lati ba awon ara ilu so, ki o fun on na ni iwe lati wa

( Wo yoku loju ewe karun )

## ELETI-OFE NG'OKE AGBA

## Keke Ologere Alupupu Alatupa Meji




OMỌBINRIN ti o ngun Kẹkẹ Ologere Alupupu ti o ni oju atupa nla meji ti itanṣan imọlẹ rẹ fẹrẹ le riran de idaji ibuso ni oru, ti o si le rin iwọn adọrin ibusọ re wakati kan ni a nwo ninu aworan yi.

## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

### VACANCIES-ELECTRICAL ENGINEER AND FOREMEN (ELECTRICAL).

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the following posts in the Engineering Department of the Authority.

**ELECTRICAL ENGINEER.**

QUALIFICATIONS :

Candidates should possess a degree, or as a minimum, Higher National Certificate, in heavy electrical engineering and should be a Graduate or Associate Member of the Institution of Electrical Engineers. Candidates must have served a full term of Apprenticeship with a recognised electrical organisation and have had subsequently at least two years experience on one or more of the following :-

- H.V. and M.V. distribution systems
- A.C. and D.C. Motors
- Ships Electrical systems
- Electric Cranes

A working knowledge of radio telecommunication system would also be an advantage.

DUTIES :

The successful candidate will be responsible to Senior Electrical Engineer for assisting in the design of electrical extensions and also for the general operation and maintenance of eelctrical equipment in the various Port areas.

SALARY :

Salary Scale 5 : £1,350 x 56 - £1,686 per annum plus Overseas pay where applicable.

**FORMEN (ELECTRICAL) :**

QUALIFICATION

Applicants should have considerable previous experience in the control of staff and should have extensive practical knowledge in at least one of the following spheres. Theoretical knowledge of the subject will also be an advantage :

- Ships electrical systems
- Factory distribution and wiring
- A. C. and D. C. Machines
- Domestic Electrical Equipment.

SALAY:

Scale 7: £902 x 56 - £1, 462 per annum.

METHOD OF APPLICATION:

Application forms are obtainable from the Personnel Manager Nigerian Ports Authority, Apapa Dockyard, and should be completed and returned so as to reach him not later than 26th November, 1961. Candidates in the service of the Government or a Corporation must submit their applications through their Heads of Departments who will forward them to the Personnel Manager along with confidential reports. Persons without requisite qualification and experience need not apply

**Bayo Kehinde**
Secretary to the Authority.

NPA Notice No. 637.
20th October, 1961.

# ITAN IBUKUN J[illegible]WOLO

(O bere loju ewe kerin )

Ibukun ti on fẹ lọdọ rẹ niyen. Ọba ni on gbọ on asi ṣe bẹ ; O tun wi fun ọba pe boya on le pẹ ki gbogbo awọn Ọlọla ti de, awọn Ijoye ki nwon ti de, ṣugbọn ti on ba mbọ wa si ọdọ rẹ, ti wọn ba fẹ da on pada, ki Ọba sọ fun won pe, ẹjẹki o maa bọ wa si ọdọ mi.

Lotọ, Ibukun pe kio to de gbogbo ena ti pesẹ patapata, ni o wa de pelu ẹwu jalajala lọrun. Bi o ti nla arin won bo ri wọn nbu pe nibo ni were yi nlọ, ara oko pada si ẹhin, o ri ẹgbẹ rẹ nibi nibi ni. O si dahun pe ọba ni on fẹ ba sọrọ, ni ọba fa gbọju soke lo ba bọ, gẹgẹbi ọrọ wọn asọtẹle. Nigbati o de ọdọ ọba, ọba ni ẹgbẹ ijoko fun u ni won ba ṣe bẹ loba joko, ko pẹ pupọ ni o ba fi ẹnu kọ ọba leti, ni won ba sọ ọrọ ti won fẹ sọ.

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

# OLOYE AKINTOLA BA AWON OMO AKEKO SORO



LONDON - Ninu ipade nla ti Oloye Akintọla ba awọn ọmọ akẹkọ bi ẹdẹgbẹta-lelẹgba enia ṣe nilu nla London ni ọjọ keji-le-logun oṣu yi ni o ti gba wọn niyanju wipe ki nwọn mura fun ati ja ogun ti yio gbe ilu wa duro.

Oloye Akintọla sọ fun wọn pe a ti gba ominira ṣugbọn iredi ominira gbigbani o ku ti a nilati dojukọ, iyẹn ni agbara iṣelu nipa iṣẹ aje ni aṣekara. Eyi ni pataki Ominira.

# Ibukun Jowolo

( O bere loju ewe karun )

Awọn ero eti lẹeye woye wipe dajudaju, ẹrẹ ọba ni eleyi iṣe. Ngbakugba nwon ba awon mejeji pẹlu ara won, ni o ba di wipe ti enia ba ṣe ẹṣẹ nla ni ilu na, to je wipe o le fa ki won pa oluware, tabi ki won ju si ewon siniye odun, won a ni o tete lọ ba ọre ọba Ibukun Jowolọ, ki o ba yan ri ọba, Ibukun na ani ṣ. lo ju ese yen lo, nwon a ni bẹ ni, Ibukun a sọ wipe yio ṣeṣe, ṣugbọn on la ri ẹrẹ on ni.

Ni yio ba on ro ẹran na ọba asi dahun wipe ki o s fun yio na won ni apo owo meji ( £200 ) Ibukun a pada lọ pe fun won ni apo mẹta. (£300). Nwon a si ko fun Ibukun, Ibukun yio koko yo apo kan sile n be (£100) ako apo meji fun ore re, ọba a tun fun ni idaji ninu rẹ.

B ni Ibukun Jowolo yi ṣe titi, ti o fi di Olowo Ọlọla, o tun kọle mọle.

O wa pe ọre re ọba yi ni ọjo kan, o ni iwo ọrẹ mi, mo dupe lowo re mo ti kọ ile moti ra ile mo ni iyawo mo ti ni ọmọ, mo tun ni ẹlẹsẹ merin (moto) mo dupe lọwo re, ki Ade pẹ lori, ki bata pẹ lese, Oba, toto. O tun sọ s'waju si pe, iba je wipe mo gba apo owo kan ijọsi lọwo re, mba ti na tan, iba je wipe mo gba ewu ti o fun mi eti salo nigbati owo ba tan, ibaje wipe ewu Etu ijọsi lowo re ni mba ti lo ya, nigbati oni ko ba de ni owo ati ra Omiran on atun pada di alakisa. Ṣugbọn Ibukun ti o fun mi ji ti ju gbogbo ohun ti o fun mi lọ. Itun nako ni wipe bi enia ko ni ile, ko lowo lowo, ti won si nfun ni ọwọ o ti ju gbogbo nkan lo.


Always ask for

'DE FACTO'

the bread with the appetising flavour



E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Wa Eleti-Ofe


## Imoran Fun Gbogbo Ọmo Ile Igbomina

Lati ọwọ Mr. A. R. O. Orilonishe Ọmọ Oke-Ọddẹ

OLOTU,

Jọwọ gba mi laye lati fi Iwe yi dupe lọwọ awọn Omọ ilẹ Igbomina ati ẹgbẹ N.P.C. Olomi. Inu mi dun lati le fun yin ni iroyin, gẹgẹbi ipade ti a pe ni ọjọ Friday 20:10:61 ni NO. 2, Eletu Iwase Street, Lagos. Ni ọjọ ipade yi, emi ni o kọkọ sọrọ nibẹ ni. Mr. S. P. Aray, mi. Oro Arakunrin wa yi je Omọ Ilẹ Oro, gẹgẹbi ẹrọ ti o sọ ni ipade ni ọjọ na, o sọ bayi wipe gbogbo ẹyin ọmọ Ile Igbomina, e je ki a ni ifi owọ sowọ ati idagba-soke nitori wipe ati sise eni elomi jina ṣugbọn ki a wa se ẹgbẹ ra ki a yọ ti ẹlẹgb de kuro nibe ki a tun Ile Baba wa ṣe.


## OPO TYRE MOTO

# TERCO

- TAYA MỌTO TI A SỌ DI TITUN
- TI OWO RẸ RỌJU
- TI ỌJA RẸ TA
- TI O SI NI AGBARA PUPO

Wa Fun Tita Ni Ṣọbu Wọnyi:-

**NIGER MOTORS**

ODUNLAMI STREET, LAGOS.

**JOE ALLEN**

TINUBU STREET, LAGOS.

**Faramobi Stores**

NO. 60, KOSỌKỌ STREET, 98 TOKUNBỌ ST, ati NO. 31, GREAT BRIDGE ST. PHONE:- 23727. LAGOS NIGERIA.

Ati ni awọn Onibara ti o gbọn ara.


## Owo Iranlowo Fun Awon Ti Ile Won Jona Ni Ije

EKO--O ta siwa leti fenrẹn wipe Igbimọ ibilẹ ilu Eko ( Lagos Town Council ) nṣe eto lati fun awọn ti ile wọn jona ni Ijẹ lẹgbẹ Obalende, ni ọjọ kọ-kan-din-lọgbọn oṣu September ti ọdun yi ni ogun pọnun fun iyara kọkan ti o jona, gẹgẹbi owo iranlọwọ fun awọn onile.

Awọn ti Lwọn haya ile gbe ti ẹhun-ini wọn ṣofo sinu ina na yio gba iranlọwọ lọdọ Igbimọ ibilẹ Eko, lori bi nwọn ba ti ri iye ohun-ini wọn si.

Awọn onile jẹ enia mọkan-le-logoje, awọn enia ti o haya ile gbe ni Ijẹ le ni irinwo enia ti o ti forukọ silẹ fun owo iranlọwọ.

A gbo pe owo iranlọwọ ti i a ti o jo ni Ijẹ yi ni nwọn yio mu ninu owo ti nwọn ti pese silẹ fun jamba ina, eyiti nwọn da silẹ larapa ina ti o jo ni Elegbata ti nwọn kede fun iranlọwọ ti ọpọlọpọ awọn enia pataki-pataki, awọn ẹgbẹ-ẹgbẹ ati Ijọba Nigeria ati okere lọwọ ninu rẹ.

Awọn egbe iranlowo ti Ijọ Aguda ( Catholic ) ti pese irẹsi fun awọn enia ti jamba ina na se, eyiti ọkan ninu wọn sọ wipe irufe irẹsi na ṣ won ni oja fun didara re. Awon ẹgbẹ Alagbelebu Pupa ti Nigeria ti fun wọn ni awọn aṣọ alokụ ( Secondhand Clothes ).

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 28, Kosọkọ Street P.O. Box 467 Phone No 20374